# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Dosumu bẹ Olotu wo

EKO.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi ni Ọgbẹni S. O. Dosunmu ti o nṣe iṣẹ alagbaṣe (contractor) ni Sẹkọndi/Takoradi Ghana wa bẹ Olotu Iwe "Irohin Yoruba" wo. Inu Olotu iwe na si dun pupọ lati ri i nitori Ọgbẹni Dosunmu yi jẹ aburo— Ọgbẹni S. M. Adẹmuyiwa ti iṣe Olotu "Irohin Yoruba".

Inu Olotu si tun dun wipe, ohun pataki ti aburo rẹ na



S. O. DOSUMU

* * *

wa ṣe ni Naijiria ni pe o ba awọn Ikọ Apapọ Ẹgbẹ Afẹfere (Action Group) wa si Naijiria lati wa ṣi awọn enia wa leti fun idibo ti nwọn fẹ di fun awọn aṣoju Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria laipe yi (Ọgbẹni Dosunmu ni aṣoju Ẹgba inu Ikọ na).

Ọgbẹni Dosunmu si ṣe ọpọlọpọ alaye fun Olotu bi gbogbo inkan ti nlọ si ni Oke Okun, Olotu ni on ko ṣẹṣẹ le ma a sọ bi gbogbo nkan ti nlọ si ni Naijiria nitoripe larin oṣu kẹsan ati oṣu kewa ọdun yi ni jijọ lo aye isimi papọ ni ile wọn l'Ago-Owu, (Isalẹ-Totoro) Abẹokuta. Lẹhin ti o ba Olotu jiroro fun igba diẹ tan ni o ba lọ pẹlu awọn Ikọ ẹlẹgbẹ rẹ, ni nwọn ba mu irn-ajo wọn pọn yika awọn ilu Naijiria.

## Ọkunrin kan ni on fẹ fi ọgba ẹwọn ṣe - ile

IBADAN.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni awọn ọlọpa mu ọdọmọdekunrin kan, Raimi Oseni, eni ọdun mẹrindinlogbọn wa si iwaju Ọgbẹni M. O. Oyemade, Adajọ Agba Kotu Kekere Ibadan na pe ni ọjọ Iṣẹgun, o fi ori ya'gba wo ile-ẹwọn ni gbogbo ọgba -ẹwọn ba daru, awọn olutọju ile-ẹwọn ati awọn ẹlẹwọn ba bẹrẹ si wa ibiti okunrin na wọlẹ si ni ọgba ẹwọn. Nigbati o ṣe ni nwọn ba a ni baluwẹ ti o sapamọ si.

Awọn ọlọpa ni nwọn ṣẹṣẹ gba iduro ọdaran na ni, nitori ti o ti wa ni itimọle fun ọsẹ meji fun ẹjọ ọlọṣa kan ti o farakọ ninu rẹ. Nigbati adajọ bi i lere ki lo ṣe ti o fi hu iru iwa bẹ ẹ, o ni "ile-ẹwọn wu u mi gbe ni, afi bi awọn ẹlẹwọn ati olutọju wọn ṣe wipe awọn ko fẹ mi nibẹ ti nwọn si bẹrẹsi lu mi ni alubolẹ". Ki nwọn to sun ọjọ ẹjọ rẹ sọjọ kejila oṣu ti mbọ, Adajọ ni on fẹ ki nwọn mu u lọ si ọgba-ẹwọn ki Dọkita le yẹ ẹ wo boya ori rẹ kope ni.

## Ikomọ ọmọ Jọlaiye dun

EKO.

LẸNULỌLỌYI ni Ọgbẹni Salami Jọlaiye ṣe ikomọ ọmbirin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ, Limọta Adukẹ lọrẹ. Ni ile wọn ti o wa ni John Street l'Eko ni nwọn gbe ti ṣe ikomọ na. Alhaji Sanni Jẹjẹ ni o ṣe akanṣe isin fun ọmọ na, nwọn si sọ o ni Munirat Bọlanle Baba ọmọ na si fijijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹye ọjọ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣẹye ọjọ na ni Alhaji Salimọnu Ọpẹloyẹru, awọn Alfa Jimọ Bọdunrin, Salawu; awọn Ọgbẹni Akande Giwa, Amadu Ọrẹmẹta J. Sulemọna Ojulari, Amuda Olukọtun, Bello Balẹ, Sanni Arẹmu ati Suberu Laoye.

Ki Oluwa da ọmọ na si ki O si fi ire kari o.

## Aṣiwaju ẹgbẹ Alakukọ wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre

AKURE.

LẸNULỌLỌYI ni Ọgbẹni D. R. Idowu, eni akọkọ ti o ti wa laye Gbakeji Alaga ẹka Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni Akurẹ ri ti fi ẹgbẹ na silẹ, o si ti wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group). O fi han ninu Iwe kan ti o gbe jade lẹhinti o ti fi Ẹgbẹ Alakukọ na silẹ pe iṣoro ati ẹru wahala ti on ti nfi ara da fun ẹgbẹ na wa kọja ohun ti on le fi ara da mọ.


OWO PỌỌKU NI OWO RẸ ṢUGBỌN O ṢE ANFANI PUPỌ . . .

ẸRỌ PHILIPS

TITUN TI O NPARỌ RẸKỌDU O NI

21 ANFANI

Price £10 : 19/- complete



Model AG1124. Without base: Model AG1024

"Oranyan" kan niyi fun ile rẹ! Agbayanu ẹrọ PHILLIPS titun ti o nparọ rẹkọdu le lo eyikeyi iru rẹkọdu ninu Redio rẹ . . . O si nṣe e fagafaga dada ni. Abajọ ti o fi ni anfani bi ọna mọkanlelogun—bẹni, ọna mọkalelogun ni! awọn anfani ti o le mu wa. Ibikibi ti o wu ti o le bẹwo, o ko le ri ẹrọ ti o nṣe iparọ miran ti o ni ọpọlọpọ anfani pupọ to gẹgẹbi owo rẹ ti kere to.

AND HERE ARE THE ADVANTAGES — ALL 21 OF THEM:

1 Suitable for both monaural and the new stereophonic records.
2 Operates on four speeds: 16.2/3, 33.1/3, 45 and 78 r.p.m.
3 Unique three-way record-changer, operating as a fully automatic record-changer or an automatic or manually operated player.
4 Automatically changes and plays up to ten 12", 10" or 7" records.
5 Even single records can be played automatically.
6 Complete push-button operation.
7 Automatic stopping device.
8 Turntable covered with thick rubber mat.
9 Can be used with any of the following Philips pick-up heads: Ceramic, Magneto/Dynamic, or the world-famous "Featherweight".
10 Record wear minimised by device to compensate the weight of pick-up head used.
11 Diamond or sapphire styli available.
12 Exceptionally constant turntable speed.
13 Very low "wow" and "rumble" values.
14 Rest position for idler wheel.
15 Fully tropic-proof throughout.
16 "Water-dipped" for extra protection against humidity.
17 Neat, compact dimensions.
18 Most attractive design, combining strength with elegance.
19 Unusually stylish colour scheme in fawn and black blending delightfully with almost any decor.
20 Superlative value for money.
21 Philips dependability backed by world-wide service facilities.

PHILIPS

Fi owo inawo diẹ gbadun agbayanu orin nipa lilo ẹrọ

PHILIPS TITUN TI O NPARỌ RẸKỌDU

Philips Nigeria Ltd., Lagos.










Eyi ni awọn ogunlọgọ enia ti o wọjọpọ lati gbọ ọrọ Oloye Awolọwọ nigbati nṣe ipolowo idibo ni Kano

# IDIBO NLA KUSI DẸDẸ

OLOTU, iba rẹ o! o tọ ki emi Ẹrukobodo kin ọ lẹhin fun alaye ọrọ rẹ ti o sọ jade s'etigbọ awọn onkawe ninu Iwe "Irohin Yoruba" ti ọjọ kẹrin oṣu yi eyiti akọle ọrọ rẹ na so wipe, "Eyi kọ ni opin ija na.

Ohun ti emi Ẹrukobodo fẹ sọ fi kin Olotu "Irohin Yoruba", lẹhin ni wipe, gbogbo wa ni a ti gbọ abayọri idibo wọle fun Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko, eyiti o ya t'ọmode tagbą lẹnu nitori gbogbo iṣẹ rere ti Ẹgbẹ Ọlọpẹ (Action Group) ti ṣe ni aṣeyọri si rere ninu ilu Eko.

## Lati ọwọ Ẹrukobodo

E maṣe jẹki idibo na ya nyin lẹnu to bẹ ẹ, ọna ti ko le fi ya nyin lẹnu to bẹ ẹ ni wipe, odindi ẹgbẹ merin ni nwọn fi ori mokun dibo ran Ẹgbẹ Alakukọ lọwọ gẹgẹbi ẹ ti ri i ka ninu ọrọ Olotu.

Ohun ti mo fẹ ki ẹ mọ ni wipe, bi awọn Agbokunkun-ṣe-ijamba na ti pọ to lẹhin Ẹgbẹ Alakukọ, sibẹsibẹ Ẹgbẹ Afẹnifẹre gbiyanju to, omi lo pọ ju ọka lọ.

Ohun pataki ti emi Ẹrukobodo nfẹ ki ẹ mọ daju ni wipe, idibo ti o mbọ yi ki iṣe idibo ran mi lọwọ, ki ran ẹ lọwọ, "idibo ọlọmu da omu iya rẹ gbe ni", ko si aye fun Ẹgbẹ Olomi lati ran Ẹgbẹ Alakukọ lọwọ, bẹni Ẹgbẹ NEPU yio ma a jijadu tirẹ lọtọ, nigbana ni ẹ o to ri i daju wipe, omi ti gbe lẹhin ẹja fun Ẹgbẹ Alakukọ ati Ẹgbẹ Olomi.

### T'OPẸ NI YIO LEKE

Pataki ọrọ mi, emi Ẹrukobodo bẹ gbogbo ẹnyin ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre jakejawo Naijiria ẹ mura giri, lai bẹru, lai foiya, ki ẹ dide dibo na fun aṣeyọri gbogbo iṣẹ ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti se fun wa kọja sẹhin ati eyiti nwọn tun ti pinnu lati ṣe fun mẹkunnu.

Adura atọkanwa mi ni wipe, ki Oluwa ki O jẹki t'Ọpẹ leke wọn. O tun digba kan na o.

## Aara san pa awọn ọmọ ile-iwe mẹwa

UMUAHIA.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ogunjọ oṣu ti o kọja yi ni aara san pa awọn ọmọ ile-iwe St. Patrick's (RCM), Igbere ni ilu Bende. Awọn mẹwa ni aara na sanpa—ọkunrin mẹjọ ati obirin meji nigbati nwọn nṣiṣẹ lọwọ. Ninu odun 1955 ni irufẹ ijamba bayi ti ṣẹlẹ si awọn ọmọ ile-iwe St. Peter's l'Eko.

## ADURA L'ẸBỌ

(Lati oju ewe karun)

Ṣugbọn nitotọ ni a ri i wipe, ọpolọpọ adura ni Etutu ti o le gba wa la lode oni, ṣugbọn bawo ni a ti le ṣe oke ti yio fi di odo? nitoripe, awọn ẹni-atijọ ti nwọn ni igbẹkẹle si adura to bẹ ẹ ti nwọn fi mọ wipe, adura nikan na ni ẹbọ, igbagbọ wọn ni wipe, ki a maṣe fi ika san ika, to bẹẹ, ti nwọn fi nkọ ọ lorin bayi pe, "Ẹ maṣe f'ika san'ka, bi'enikan ṣe nyin nika, ẹ roka fun un ko jẹ o". Nitorina, nwọn ni bi a ko ba ṣe bi ti nṣe, ko le ri bi o ti nri o Eke ni o de ile aiye lode toni o.

Ṣugbọn sibẹsibẹ na ẹwẹ, ẹ ma gbagbe o, egbe kan ko tayo ka gẹṣin, ajabo kan ko tayọ ọpọ enia, afẹẹri kan ko si tayọ ki a fi igbo nla bojụ, Ọran kan ko le tobi titi aiye, ki o tobi ju adura lọ, adura l'Ẹbọ, adura l'Etutu ohunkohun yalaa ni buburu tabi ni rere ninu igbesi-aiye awa ọmọ-enia,

Njẹ, ki a fi rere pade ni ọjọ ọjọ-miran ọjọ rere.



O DARA LENU

YIO SI FUN O NI AGBARA



Phosferine Tonic Wine je agbo pataki ti nfun ara ni okun. Mu lojojumo. Yio mu ayo ba o lwo yio si ri orun sun daradara. Ra igo re kan lowo awon ti nta a nisisiyi!

**Akiyesi pataki fun awon aboyun.**

Phosferine Tonic Wine ki panilara. Ko si eran tabi ohun ti a yo kuro ninu eranninure.

PHOSFERINE TONIC WINE

*agbo ti o gbadun . . . mejetitun nla - yio se o ni ire.*

# Ẹgbẹ Afẹnifẹre gba ẹdẹgbawa Alabojuto fun idibo Ipinlẹ Ariwa

[illegible]

## Obirin ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre yan Sode fun Idibo Pọta

[illegible]

## Orukọ awọn ti yio dibo Apapọ Ijọba Naijiria

Lati oju ewe keji

[illegible]

## AKIYESI PATAKI

[illegible]

OLOTU.








# Awọn ara Kano fi ayọ gba awọn Ikọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre lalejo



Eyi ni awọn ẹgunlọgọ enia ti o wọjọpọ lati gbọ ọrọ Oloye Awolọwọ nigbati nṣe ipolowo idibo ni Kano



Eyi ni ipade ipolowo idibo ti Ọgbẹni S.O. Shonibare, Akowe Agba-Apapọ Egbẹ Afẹnfẹre ba wọn ṣe ni ilu Dawaku - Tofa ni Kano

Ẹ DIBO FUN ỌPẸ



Alhaji Jamilu Dantata aṣoju ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre yan lati dibo fun ni Kano ni o mba awọn enia sọrọ ni ipade yi ni ilu Kano





[illegible]

Fun alafia ati itura mo a lo ỌṢẸ ALAFIA LIFEBUOY nigbagbogbo.

## Ẹniti o wọ Reluwe laigbawe fi £7 tanran

IKEJA.

LENULOLOYI ni Adajo Kotu Kekere Ikeja ri i pe, ọdaran kan Jonathan Okusanya, ẹni ọdun mejileladọta ti o nṣiṣẹ oluko ni "Christ the King School", Mushin jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe o lọ ji ọkọ reluwe wọ lati Oshodi si Mushin laigba iwe ọkọ (kọbọ meji pere ni iwe ọkọ na) ni owurọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu ti o kọja yi ni o ba fi ni ki o lọ fi pọnun meje (£7) tanran na.




## BIBELI MIMỌ T'ỌRUN ỌWỌN IṢURA T'EMI

# Iwọ yio jẹ iṣẹ ọwọ rẹ

### Lati ọwọ Evangelist Akande, Ogbomọṣọ

**ESẸ wura wa ti oni yi ni eyiti Dafidi sọ ninu Orin Dafidi ori 128, ẹsẹ 2, bayi pe, "Iwọ yio jẹ iṣẹ ọwọ rẹ". Ọrọ na jẹ ọrọ ti o wuwo, o si jẹ gbolohun ọrọ ti o dun pupọ, bakanna ni o si tun koro.**

Ninu aiye yi, oriṣi enia meji lo wa nibẹ, ọkunrin ati obirin, enia rere ati enia buburu. Bi gbolohun na, "Iwọ yio jẹ iṣẹ owo rẹ", ba dun fun enia rere, o daju pe, ko le jẹ didun fun enia buburu. Bi a ba sọ fun enia rere pe, "Iwọ yio jẹ iṣẹ owo rẹ", ayọ ni yio fi wipe "Amin", nitoripe iṣẹ owo rẹ dara, o si dun jẹ, ṣugbọn bi a ba wi fun enia buburu pe "Iwọ yio jẹ iṣẹ owo rẹ", o daju pe inu rẹ ki yio dun lati ṣe "Amin", nitoripe o mọ pe iṣẹ owọ on buru, o si koro, ko si ṣe e jẹ.

Mo fẹ ki o da nyin loju gbangba pe olukuluku ni yio jẹ iṣẹ owo rẹ, yala rere tabi buburu. Ninu aiye yi, enia rere ati enia buburu lo jọ wa nibẹ, awọn mejeji ni Ọlọrun si fun ni aye lati ṣe iṣẹ ọwọ wọn, nitorina ni a fi sọ ninu Matteu ori 13, ẹsẹ 30, bayi pe, 'Ẹ jẹki awọn mejeji ki o dagba pọ titi di igba ikore". Irugbin ti a gbin, nigbati o ba so dada tan a o ka a fun jijẹ ni akoko ikore, bẹni olukuluku enia rere ati enia buburu mbọwa jẹ ere iṣẹ ọwọ wọn nigbati akokona ba de.

O le pẹ, tabi k'o ya, ṣugbọn o daju pe olukuluku ni yio jẹ iṣẹ ọwọ ara rẹ, nitorina ni Ọlọrun fi sọ ninu Isaiah ori 3, ẹsẹ 10 ati 11, bayi pe, "Ẹ sọ fun olododo pe, yio dara fun un, nitori nwọn o jẹ eso iṣẹ wọn. Egbẹ ni fun enia buburu, yio buru fun un nitori ere ọwọ rẹ li a o fi fun un."

Ọpọlọpọ awọn enia buburu ni nwọn ti fi ọwọ ara wọn ṣe nkan buburu lati fi ṣe ẹnikeji wọn ni ibi, ti ibi na si padada le ori ara wọn. Fun apẹrẹ, ẹ ka Iwe Esteri ori 5, ẹsẹ 11 titi de 14, bi Hamani ti jẹ enia nla to, sibẹ enia buburu ni, o si fẹ ṣe ibi si Mordekai lati pa a, nipa bẹ ẹ, o fi ọwọ ara rẹ ri igi kan mọlẹ ti o ga ni adọta igbọnwọ lati fi Mordekai rọ sori igi na.

Ṣugbọn ẹ tun lọ ka Esteri ori 7 ẹsẹ 1 titi de 10, Hamani di ẹniti Ọba binu si, Ọba si nwa ohun ti yio fi pa Hamani, nigbana ni ọrọ na ṣẹlẹ ninu Esteri 7: 9-10, bayi pe, "Harbona ọkan ninu awọn iwẹfa si wi niwaju Ọba pe, sa wo o, igi ti o ga ni adọta igbọnwọ ti Hamani ti ri 'tori Mordekai, o wa ni iduro ni ile Hamani, Ọba si wipe, ẹ so o rọ lori rẹ, nwọn si so Hamani rọ sori igi na ti o ti ri fun Mordekai." Dajudaju otitọ ni ọrọ ti a sọ ninu Owe ori 11: 5, bayi pe, "Enia buburu yio ṣubu ninu iwa-buburu rẹ." Ati ninu Owe 14: 32, bayi pe, "A pa enia buburu run ninu iwa-buburu rẹ."

Nitorina, ẹnyin arakunrin ati arabirin nibi gbogbo, ẹ jẹki a kun fun iṣẹ rere nigbagbogbo, ki a si ma a ranti ọrọ ti a sọ ninu Galatia ori 6, ẹsẹ 7, bayi pe, "Ohunkohun ti enia ba funrugbin, on ni yio si ka". Jẹki ọwọ rẹ ma a ṣe iṣẹ rere ti o dun, ti o si ṣe e jẹ, nitoripe o daju gbangba pe, "Iwọ yio jẹ iṣẹ ọwọ rẹ".



# Akiyesi awọn Awo-Irawọ nipa Ọjọ-Ibi

AWỌN nkan wọnyi ni yio ṣẹlẹ larin ọsẹ yi lati December 6th si December 12th, 1959.

## CAPRICORN
**(Dec 21st-Jan 19th)**

Sinmi ki o si jẹ anfani ti wa a ri ninu ọsẹ yi nipa kikegbepọ. Maṣe ti fi okan si awọn eto ti o nse lati ni losiwaju. Ma a jaiye, ma a fi igbadun s'ayọ, ki o si ma a sinmi lasiko yi.

## AQUARIUS
**(Jan 20th-Feb 18th)**

Wa a ri i pe iṣẹ rẹ yio wa rorun lẹhin ojo Iṣegun. Sa gbogbo agbara rẹ lati pa eṣu awọn olori kikun enia, o ti bẹrẹsi ni awọn ọrẹ atata, wa a si mọ ododo yi nipari ọsẹ yi.

## PISCES
**(Feb. 19th-Mar 20th.)**

Wa a ma a gbajumọ siwaju ati siwaju lojojumọ. Wa a ri i pe awọn enia pataki pa a ma a ni ifẹ si ẹ. Bi iwọ ba farabalẹ dada ti o si nse ododo wa a ti ipa wọn ni ilosiwaju pupo larin ọsẹ diẹ tombọ yi.

## ARIES
**(March 21st-Apl 20th)**

Fi ọkan rẹ si iṣẹ ki o si ṣe e dada, o ni iṣe abamo nipa rẹ ninu oṣu tombọ yi. Wa a si ṣe anfani ninu Odun Titun. Bi o ba ni awọn enia ni awọn ilu okeere, wa a gburo pupo nipa wọn ki ọsẹ yi to pari.

## TAURUS
**(Apl. 21st-May 20th)**

Ninu ọsẹ yi wa a ri ohun idunnu pupọ lati ọdọ awọn t lo sunmọ ẹ. Ẹnikan ti ki i fẹ gbọ ti ki i fẹ gba wa a bẹrẹsi huwa ọmọluwabi si ẹ. Wa gburo nipa owo rẹ kan ṣugbọn o le ma tete to ẹ lọwọ.

## GEMINI
**(May 21st-June 20th)**

Eto lati gbe iyawo tabi fun iṣẹ atata kan yio duro sinṣin ninu ọsẹ yi. Bi ẹ ba ti pari eto na, wa a ri i pe o ni abọ iṣẹ lati ṣe pari. Wa a ri i pe wa a ronu jinlẹ ninu ipari ọsẹ yi ju ti atẹhinwa lọ.

## CANCER
**(June 21st-July 20th)**

Wa a ri owo ninu awọn ayipada ti yio ṣẹlẹ lẹnuloloyi, wa a si mọ ki ọsẹ yi to pari pe awọn yio wulo fun ẹ. Wa a ni ilosiwaju pupọ laseko yi bi o ba farabalẹ lati ṣe ohun ti o tọ ati eto dada.

## LEO
**(July 21st-Aug 21st).**

Wa a gbadun irin-ajo kan ti wa a rin. Ninu irin-ajo na wa a ṣe alabapade ẹnikan ti yio si di ọrẹ rẹ atata. Nipari ọsẹ yi wa ri i pe o ni lati ṣe iṣẹ koja eyiti o ti nṣe ri. Wa a gbadun awọn ẹbi re ti ẹ jijọ ngbe koja ti atẹhinwa larin ọse yi.

## VIRGO
**(Aug. 22nd-Sept 22nd)**

Ile rẹ yio kun fun asiki pupọ. Wa a tun rẹ dada pẹlu ọrẹ atijọ kan 'e aye ti ẹ o fi ṣe igbeyawo pọ. Wa aa ni owo (money) ninu owo (trade) kan t lo ti ṣe ti pẹ tabi nipa owo ti o ti ko si ori ọja kan ti pẹ tabi nipasẹ ẹbi rẹ.

## LIBRA
**(Sept 23rd-Oct 23rd)**

Owo a to ẹ lọwọ ju eyiti o ri lẹnuloloyi lọ. Larin ọsẹ yi edeaiyede ti o wa larin rẹ ati ẹnikan ti o sunmọ e pẹkipẹki yio pari. Gbọ imoran awọn ẹbi rẹ ti nwọn ni ifẹ si ẹ ti nwọn si nfẹ 'fẹ rere.

## SCORPIO
**(Oct. 24th-Nov 22nd)**

Wa a fi ọkan si ọran owo ju ti ohun miran ti o nṣe ẹ lara lọ, ni ibẹrẹ ọsẹ yi. Bi o ba ti yanju awọn ọran rẹ pataki, wa a tun bẹrẹsi ro awọn ohun miran pataki lati muṣẹ. Wa a ri idunnu laipe yi.

## SAGITTARIUS
**(Nov. 23rd-Dec. 20th)**

Ere ti o ri jẹ lẹnuloloyi yio mu ẹ ṣe inawo kan lori awọn ẹbi rẹ. Ni ipari ọsẹ yi wa a ni ilọsiwaju ninu iṣe rẹ. Nipa bayi wa a gbadun pupọ titi ọsẹ diẹ tombọ yi. Sa gbogbo agbara rẹ lati ṣe dada si awọn ti o tọsi ni ile rẹ ati ibiṣẹ rẹ.

# Ara Ilọrin ẹ dibo f'Ọpẹ

EJOWO gba mi laye lati dupẹ lọwọ Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre fun awọn nkan rere ti nwọn ṣe si ilu Ilọra Nwọn ni "bi ọmọde ba dupẹ ore ana a si tun ri omiran gba." Awọn nkan miran ti a tun nfẹ bi nkan ilosiwaju ni'lu wa na ni omiẹrọ ati lẹntiriki.

Mo mọ daju pe, Oloye Obafẹmi Awolọwọ, Alakoso Ijọba na ki i ṣe ileri ki o ma mu u ṣẹ.—Ẹnyin ara Ilọra, ẹ jẹ ki a dibo fun Ọpẹ.

Emi ni,
S. T. ADEYẸMI.
Ilọra, Ọyọ.

# Ijẹbu-Ijẹsha dupẹ lọwọ Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre

GBOGBO awa ara Ijẹbu-Ijẹsha fi tayọ-tayọ dupẹ lowọ Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ipinlẹ Iwọ-Orun fun ti oda ti nwọn yọ si titi mọto ti o la ilu wa kọja lọ si Oke-Imẹsi. Lati fi ẹmi imore wa han, o yẹ ki gbogba awa ara Ijẹbu-Ijẹsha tile-toko parapọ dibo fun aṣoju ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ba yan sode lati dibo fun wọle Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ti o mbọ yi. Ẹnyin ọmọ iya mi, Ẹ DIBO F'ỌPẸ o.

Olotu, aṣeye ni alakan nṣe epo, ẹ o ma a lọ're, ẹ o si ma ri ile desi.

Emi ni,
D. D. AROJOJOYE.
Idọgọ Railway Station.

# Aderoju ati awọn ọmọlẹhin rẹ fi Ẹgbẹ Alakọku silẹ

KISHI.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu kẹsan ọdun yi ni Ọgbẹni Shitu Aderoju, ọkan ninu awọn aṣiwaju Ẹka Ẹgbẹ Alakukọ Kishi ati awọn bi adota enia ninu Ẹgbẹ Alakukọ na, gbogbo wọn si wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group).

Ọgbẹni Aderoju ni idi ti on fi fi Ẹgbẹ Alakukọ silẹ ati awọn ọmọlẹhin on ni pe, itanjẹ po pupọ ninu ẹgbẹ na bẹẹsi ni idawo ojojumọ laimo pataki ohun ti nwọn nfi owo na ṣe ati wipe, awọn ri i wipe Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o to fi ọkan tẹ fun Ominira Ijọba Apapọ Naijiria.




# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA



Aworan yi ni ti awọn Ijoye 'Iu Ghana ti nwọn wa si Accra lati pade Oloye Edinborọ ti nṣe ọkọ Ọbabirin Gẹẹsi

## Aṣiwaju Ẹgbẹ Olomi kan ni lati san £485 fuu Aṣiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre kan

BAUCHI.

NI ọjọ 'Ru ti ṣe ọjọ kọkanla oṣu ti o koja yi ni Adajọ Kotu-nla Bauchi ṣe idajọ pe ki Wakilin Tsaffa, Aṣiwaju Ẹgbẹ Olomi (NPC) Bauchi ati awọn mẹtala ninu Ẹgbẹ Olomi lọ san £485 10s. 11d. fun Mallam Ibrahim Dimis, Aṣiwaju Ẹgbẹ Habe Peoples Party dapọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Ọgbẹni Ọlatunji Fagbe fun nkan wọn ti nwọn bajẹ ninu ija-igboro kan ti Ẹgbẹ Olomi da silẹ.

Adajọ na si ni nwọn ni lati san £102 18s. owo-irinṣẹ fun awọn aṣaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nwọn ba nkan wọn jẹ na. Iya owo ti awọn aṣiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre na pẹjọ fun lati gba fun awọn nkan wọn ti nwọn bajẹ jẹ £2.5000 ki Adajọ na lọ da si iye ti a fi soke yi. Ọgbẹni S. O. Morundiya, agbẹjọro awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o wa ni Bauchi ni o ṣe ẹjọ na.

Laipẹ yi ni Adajọ Kekere kan tun ṣe idajọ fun Umoru pe ki o lọ san pọnun marundilọgorin (£75) owo ibanilorukọjẹ fun Ọgbẹni Patrick Ede fun sisọ ti o sọ ọ s'ẹwọn ni ọna aitọ.

## Ayọkunnu Sọmọlorukọ

NYNFOMANO, GHANA.

NI ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni Ọgbẹni Amos Okunlọla Ayọkunnu ṣe ikomọjade ọmọbirin kan ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ, Janet Ajibikẹ lọrẹ, nwọn si sọ orukọ ọmọ na ni Deborah Abẹgbe Okunlọla, baba ọmọ-tuntun na si fi ọpọlọpọ onjẹ ati ọti tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun. Ọgbẹni Z. B. Wereniṣẹ-Oluwa ti o jẹ baba fun baba ọmọ na ṣe gudugudu meje, o si nawo-nafa nibi ikomọ na.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Ezekiel Babatunde, Raimi Ṣiyanbola, B. Amoda, Ezekiel Adesoye, Ṣekoni Israel Aṣiyanbi, Barber Paul Adewuyi, Joseph Adebowale, M. S. Folorunṣọ, M. Ajisafẹ, Hezikiah Asunmọ, Amos Oyewuwo, M Balogun, Gbadamosi Ajia, awọn Iyaafin Rutu Ibijoun, Alice Mojoyinola, Lydia Faderera, ati Alice Ebo-ọla. Ki Oluwa da ọmọ na si, ki o ṣẹ fi rere kari o.

## *Adajọ sọ Ọlọọla kan s'ẹwọn ọduu meji*

KADUNA.

LAIPẸ yi ni Adajọ-Agba, Ọgbẹni A. J. Price ti Kotu kekere ju ọkunrin Ọlọọla kan, David Ogah, s'ẹwọn ọdun meji nitori ọran ti ọmọ ti o kọ'la fun ti o ku mọ l'ọwọ. Ẹjọ ti awọn ọlọpa ba ro nipe ninu oṣu kẹwa ọdun yi, ọlọla yi kọ'la fun ọmọbinrin kekere kan ti orukọ rẹ njẹ Anamakoronye Okafor, ọmọ ọdun meje.

Bi ọ si ti kọ ila yi tan ni ẹjẹ bẹrẹsi ru jade lara ọmọdebinrin na titi ti ọmọ na fi jalaisi. Adajọ ni o yẹ ki a pa aṣa-iṣẹdalẹ ti ko ba ọjumu rẹ. Awọn ti ko ba nṣe oniṣegun atata ko gbọdọ ṣe iru nkan bayi nibikibi ni agbaiye. Awọn ilu ti o laju ko tilẹ nṣe e rara.


ẸKUN-AGBARA
egbogi aladun
da ikọ rẹ duro
ki o si f'alafia f'agbara rẹ




Fun iwosan iko kiakia ati l'alafia fun inu ati agbari rẹ, mu Sante Pastille. Awọn egbogi aladun, ti o lagbara ti o si dun yi yio tete mu ki o gbadun pẹlu ipanu.

SANTE PASTILLES

MADE BY ROWNTREES IN ENGLAND





Iye awọn ọmọ ti o nlọ si ile-ẹkọ ni Ipinlẹ Iwọ Õrun Naijiria tubọ nga si lọdọdun. Awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin ti nlọ si ile-ẹkọ giga ni ọdun 1959 ni Iwọ Õrun Naijiria jẹ ọkẹ marun-din-lọgọta o le ẹgbarun ati ẹrinladinirinwo (1,110,386). Eyi ni pe ọkẹ mẹta ati ẹgbẹje o din mẹdọgbọn ọmọ (70,375) ni o fi le si iye ti mbẹ ni ile-ẹkọ ni ọdun t'ukọja. O si tun han gbangba pe iye awọn ọmọde ti o nlọ si ile-ẹkọ kekeke ati ile-ẹkọ giga (secondary modern) tun nlo si lọpọlọpọ.

Awọn ọmọde ti o nlo anfani ẹkọ ọfẹ nisisiyi jẹ ọkẹ mọkanleladọta ati ẹdẹgbaaan o le ejila-dinirinwo (1,037,388), ọkunrin jẹ ọkẹ mejilelọgbọn ati ẹgbẹrinla o le mẹrindilọgọta (642,856), obirin si jẹ ọkẹ mọkandilogun ati ẹgbaje o le ojilelẹdẹgbẹta o din mẹjọ (394,532), eleyi si yatọ si ọkẹ mọkandiladọta ati ẹgbẹfa o le ọtalelẹgbẹrin o din marun (982,755) ti nlo anfani na ni ọdun 1957. Awọn enia si tun nbere fun didasilẹ ọpọlọpọ awọn ile-ẹkọ giga (secondary modern). Ọkẹ meji ati ẹdẹgbẹjọ o le meje (43,507) ni awọn ọmọ ti o wa ni ile-ẹkọ giga (secondary modern), ọkunrin jẹ ọkẹ kan ati ẹgbafa o le ọtalelẹgbẹrin ati mẹsan (32,869), obirin jẹ ẹgbarun ati ojilelẹgbẹta o din meji (10,638), eleyi si yatọ si ọkẹ kan ati ẹgbẹjọ o le meji iye ọmọ ile-ẹkọ ti o wa ninu ọdun 1957.

Awọn ọmọ ti o nlọ si ile-ẹkọ giga (secondary grammar schools) jẹ ẹgbasan ati ẹdẹgbẹrin o le mẹrinleladọta (18,754) ọmọdekunrin jẹ ẹdẹgbajọ ati ẹgbẹrin o le mẹtadilogorin (15,877), ọmọbirin jẹ ẹgbẹrinla o le mẹtadilọgorin (2,877); bẹni awọn ọkunrin ati obirin ti o nlọ si ile-ẹkọ giga ti a ti nkọ awọn olukọ (grade II) jẹ ẹgbaji ati mejidinladọje (4,128) ati pe awọn ti nkẹkọ ni ile-ẹkọ miran ti a ti nkọ awọn olukọ (grade III) jẹ ẹgbẹtalelẹgbata ati mẹsan (6,609).

O fẹrẹ jẹ pe gbogbo awọn ile-ẹkọ ti o wa ni Iwọ Õrun ni Ijọba nran lọwọ. Ijọba ti naapa rẹ lati dojukọ kikọ awọn olukọ ti yio kari gbogbo awọn ile-ẹkọ ti ngberu si. Ni ipari ọdun yi, awọn akẹkọ ti yio pari ẹkọ wọn lati ile-ẹkọ ti olukọ gbogbo yio jẹ ẹgbaji ati ọtalelẹdẹgbata o le mẹrinla (4,574), a si nireti pe nwọn yio mura lati ṣe iṣẹ wọn gẹgẹ bi olukọ pataki ni awọn ile-ẹkọ gbogbo.

Ile Iṣẹ ti nkede Iṣẹ Ijọba Iwọ Õrun Naijiria l'ogbe ọrọ yi jade.

